# EKO AKETE.

## IWE IROHIN ỌSỌSẸ.

ỌRỌ IFÓJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL. II. NO. 53. SATURDAY, JULY 14, 1923. FOURPENCE.

---

### ỌGBẸNI OYINBO F. A. PICKLES

nṣe *Cinema* ni Opopọ nla lẹmẹta lọsẹ. Awõ-ṣẹju ni awọn aworan rẹ. Ina Manamana ti a si fi nṣe Ẹrọ na mọlẹ bi ọsangangan. Ọrẹ, lọ fi onjẹ oju f'oju nibẹ. Ẹmẹta lọsẹ lo nṣe e *Monday, Wednesday* ati *Saturday*, ni agogo mẹjọ abọ alẹ (*8.30 p.m.*)

---

### A. KESSLER,

19 JUL. '23

ILE OWO OYINBO GERMAN HAMBURG

Iwọ le ranṣẹ Ẹrọ-Iranṣọ "*Mundlos*" ati "*Adler*" nibẹ bẹ si ni Ẹrọ-riran bata pẹlu.

Ẹ tọ Ọgbẹni A. Kẹssler lọ ni 7 Labinjọ Lane, kọrọ Williams Street.

**Mundlos on top Mundlos.**








**Mundlos on top Mundlos.**

A nranṣẹ orisirisi ọja fun enia to tete nlọ nilẹ ni *Nigeria*

Ọja tiwa ya. A si ni ọja wọnyi fun tita:—Ohun ẹrọ orin, Awo-Abọmafọ, Kẹkẹ-ologere t'Ọkunrin t'Obinrin, Waji.

Ẹ le ri Ẹrọ Iranṣọ "*Mundlos*" ra lọdọ J. S. Johnson, Alhaji Masu, ati lọdọ H. Campos ti Campbell Street.

LAGOS STEVEDORING COMPANY.

ALL STEVEDORING WORK

undertaken at lowest possible prices anywhere in the Lagos area.

GOODS HANDLED CAREFULLY AND EXPEDITIOUSLY.

Estimates given for the handling of goods under any circumstances.

*PRICES ON APPLICATION*

TO

**S. J. M. Johnson,**
9, Scale Square,
Phone 227 Lagos,
P.O. Box 498.

---

ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun ikole fun tita ni owo opoku-oyoku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorisirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onisowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo po o.

---

ỌGBẸNI DURO THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, ita Faji, l'Eko, ni orisirisi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ọgbẹni D. B. OṢUNTOLU, onisowo Ọlaorewaju
ti ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni
No. 44 Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets
Panu ikọle, Aṣọ oniruru, Itẹkọ, Baranjẹ,
Olowonyọ, Yọmini, (*Sallen.*)

Ati orisirisi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju
o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

**Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.**

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati

MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onisowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mãse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

**Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.**

*Editor & Proprietor* :—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

—:o:—

### ỌPELẸNGẸ NI'YAWO ỌMỌ—ATOTILE TỌ.

Ni *Thursday* to nbọ ti o jẹ ọjọ 19 oṣu yi. Ọgbẹni B. C. Vaughan Atotiletọ ati Mrs. rẹ ti Ita Agarawu, yio sin ọmọ wọn omidan Ellen Beatrice Bamijoko; Awẹlẹwa ọlọrun-sẹgi, ni'yawo fun Ọgbẹni Emanuel Fọlarin da Silva, ọkan ninu awọn Akọwe pataki ni Ile Ita-iwe awọn C.M.S. nibi, ni *Church* Baptist nla ni Opopo-nla ( *Broad Street* ) ni agogo meji ọsan ọ'ọ na; lẹhinna nkan a ṣ'ẹnu re fun awọn ti a ti fi iwe-ọla pe ni gbangan Ile awọn Ẹgbẹ Aṣiri ti a npe ni St. George's Hall ti ko jina si *Church* na; Ki Baba m'ọjọ ro!

### IRAN MBẸ NI'LE AD'ẸRUP'ỌKỌ O JARE, ẸNIKEJI!!!

Ko-si-b'o-ti-ri ni Ariya ti Alufa Ẹni-ọwọ R. A. Coker ṣe l'ana ni 33 Princes Street ( Isalẹ Gangan ) ni'le Ọgbẹni M. O. Coker Akuru yẹ'jo ọmọ Ad'ẹrup'ọkọ, nigbati Ẹni-ọwọ na di Ẹni ọgọrin ọdun, *Biskop* Oluwọle pẹlu awọn Alufa ẹmẹwa rẹ ti C.M.S. wa ṣe akanṣe isin fun u, *Biskop* si fun u ni Onjẹ Alẹ Oluwa, pupọ ninu awọn Sanmari Eko ni a pe sibi ajọyọ yi, awọn to si pe wa lati Ilu Oke ko aiye ti onjẹ npe onjẹ ranṣẹ, aṣọ ẹbi iyẹn ọgọrọ, awọn afunfere ( *Philharmonic Band* ) si fun wabi wọsi ninu fere wọn. Bẹ si ni awọn oriṣiriṣi ilu bi Apọnran, Samba, Achiko nsọ ti ẹnu wọn, a gbọ pe gbogbo awọn ẹbi Ẹni-ọwọ na pẹlu awọn ọmọ rẹ lo pesẹ sibẹ perepere ti gbogbo rẹ ndun yungba lati arọ di alẹ. A ki Ẹni-ọwọ yi ku'nawo, a ṣeyi ṣ'amọdun o. A si ki Ọgbẹni M. O. Coker ọkunrin jẹjẹ abi'ja kunkun ati Mrs. rẹ, Ẹ ku aṣeyẹ ọjọ.

### EWO L'EWO ẸNYIN A F'ABẸRẸ P'IDAN?

Oyinbo aranṣọ kan ṣẹṣẹ de si ilẹ yi ni lọlọ yi, o si fi apakan ile-ọja awọn oyinbo *Fairley* onişowo ṣe ibi'ṣẹ rẹ. Ni ọjọ diẹ t'o de na, a gbọ pe ọwọ rẹ ti rẹn fun iṣẹ, a si sọ pe wiwọ ni awọn alagbaṣiṣẹ ( *Journeymen* ) ati awọn ọmọ ṣẹ nwọ lọdọ rẹ. Agbalagba dọwọ nyin o, ẹnyin enia wa aranṣọ ti ẹ nfi iṣẹ oniṣẹ ja'fara.

### DANIEL WILLIAMS, ỌRUN'RE O!!

! Tẹduntẹdun la fi jihin iku Ọgbẹni D. J. Williams Akọwe Ọwa ati awọn Igbimọ ti o ṣẹlẹ ni Ileṣa ni ọjọ *Friday* ọsẹ to kọja. Ọga, Olukọni ni Ile Iwe Alapako ( *St. Peters* ) ni Ọgbẹni na nigba atijọ, lẹhinna a gbe e lọ si Ile Iwe Faji, gẹgẹ bi olori nibẹ pẹlu, nigbati o si fi iṣẹ na silẹ, o lọ ṣe Akọwe Ọwa ni Ileṣa fun ọpọlọpọ ọdun. A ba awọn Ẹbi Alagba yi kẹdun ọfọ yi.

### EYI NKỌ? AWỌN ỌB'AIYEJẸ B'ỌRUN SE JẸ!!!

A gbọ pe ni aipẹ yi awọn obinrin ara Sobo meji nja nitori ọkunrin kan tobẹ ti o fi jẹ pe ẹnikan ninu wọn fi ata ti o ti lọ rẹ ẹnikeji rẹ loju, iyoku iregbe ọrọ yi di ti Kotu ọlọpa nibi, Adajọ si da ẹbi fun ẹniti o ṣe jamba na pe ki o san ( £5 ) si apo Ọba ni wara-ṣẹṣa.

### NIGBAWO NI MAKU KO NI KU?

A gbọ pe nwọn ko iti pe Ọgbẹni Charles Ọbafẹmi si iṣẹ *Lawyer* gẹgẹ bi a ti sọ fun ni ni ọsẹ to kọja, a gbọ pe awọn ọgunna gbongbo ofin na yio pe e, ki ọdun yi to pari.

### A B'ONIYAWO ȘE'YAWO, O YE!

Ọgbẹni J. A. Oyegbọla ti 11 Cole Street Ebute Mẹta yio fi ọmọ rẹ obinrin Christiana Ọmọlara f'ọkọ, fun Ọgbẹni Emanuel Babatunde Macauley ni ọna tiwa (*Parlour Marriage*) ni *Sunday* ọjọ 22 oșu yi ni Ebute Mẹta; ọjọ a ro o!

### KABỌ, ỌMỌ ARAMFẸ.

A ki E. A. Adeyẹmi Ọmọ-Alade Ifẹ kabọ; Ọmọ-Alade na de si ilẹ yi ni ọsẹ t'o kọja fun ișẹ kan pataki; o si wọ si No. 6, Ipaiyẹ Street, ni Isalẹgangan.

### AKINRẸMI, A BA Ọ YỌ.

A ba Ọgbẹni James T. Akinrẹmi White ti Ita Akanni Agoju awọn Oyinbo Overmann ti Ilu Ọba yọ fun ẹni ọdun 21 ti o da ninu ișẹ awọn Oyinbo na ninu oșu yi. Ọgbẹni White fi ọdun mẹta șe Akọwe labẹ wọn o si fi ọdun 18 șe Aṣoju (*Agent*) wọn, ipo na lo si wa titi di oni. A ki ọ ọrẹ, o ku ewu ọdun.

---

## ORIN NI OHUN ILẸ WA.

Iṣẹ titobi ni lati wa ọrọ ti yio ba awọn orin ni ohun ilẹ wa mu dede; nitorina, bi a ba ri ẹnikan ti o șe (*compose*) ohun orin pẹlu ọrọ ti o ri rẹmu, o yẹ ki a fi tifẹ-tifẹ tẹwọgba a laisi iyipada.

Mo ranti ajọdun ti awọn Ijọ kan șe, nwọn fi ọkan ninu orin *Brotherhood* kọn awọn orin aṣayan fun lilo; ki nwọn to pari oniruru awọn ipade ti o faramọ ajọdun na, diẹ ninu awọn ara Ijọ bẹrẹ si kun sinu nitori orin *Brotherhood* kan ti nwọn ko fun sa mọ. Nigbati mo fi'ara-fisilẹ lati wadi rẹ wo, a sọ fun mi pe nitoriti ẹkọ awọn ti nlo irufẹ orin bẹ ko ba ti Ijọ wọn mu. Njẹ mo bere, a ko ha ri meji tabi ju bẹ lọ ninu Iwe-orin ti Ijọ C.M.S. ti a nkọ titi di oni yi, ti o jẹ pe awọn ti ko tẹlẹ igbagbọ t'Ọlọrun Mẹtalọkan li o șe wọn?

A sọ fun mi nipa awọn orin meji wọnyi:—

1. 'Wọ Imọlẹ larin okun aiye

ATI

2. Ng o sunmọ Ọ Ọlọrun

wipe awọn Ijọ ti ki iṣe *Trinitarian* li o șe wọn.

Mo yo lati ri akiyesi ti Oniwe-irohin yi kọ si isalẹ takada mi ninu iwe rẹ ti ọjọ Saturday, June 23rd, 1923, wipe:—"*Ajulọ ha pin sọdọ ẹnikan bi?*" Dajudaju ni ajulọ ko pin sọ ẹnikan, nitorina ni ko șẹ yẹ fun ẹnikeji lati ki ile sori ipilẹ ti ẹni kini ba fi lelẹ.

Iru apẹrẹ ti a nfẹ ni awọn orin meji wọnyi lati ọwọ awọn enia meji ti ohun wọn dọgba, șugbọn ti ọrọ wọn takete si ara wọn. Ibẹrẹ ohun orin na lọ bayi:—

$\frac{3}{4}$ time
d :— m | l : s | d : m | m : r —||
m :— s | d : d — | l — : — d :
r :— m | d : d — | — : — : —||

Ibẹrẹ ọrọ orin lati ọwọ ẹni kini lọ bayi:—

Ẹnyin ero Ijọ wa o,
Ẹ ma fo'ya, a o.—(*2 times*)

Ibẹrẹ ọrọ fun orin kanna lati ọwọ ẹnikeji lọ bayi:—

Baba mimọ, gb'adura mi:
Gba mi Baba; gba mi, gba mi Baba.

*Bẹbẹ ni ki a ma ri o.* OYENẸYẸ.

1. A ki yio ba Oyenẹyẹ fa ọro ipilẹ-ko-șe-ipilẹ to fẹnu kan ninu Iwe rẹ ọsẹ yi si wa, nitoripe Ọkọwe (*Correspondent*) wa miran, A. Ọla. Ajib. ti gba ina oju rẹ nipa alayé rẹ to wa ninu iwe wa ti ọsẹ to kọja.

2. A fẹ tun ọrọ ti Oyenẹyẹ sọ nipase ti ẹniti o ni o ro (*compose*) orin "Iwọ Imọlẹ larin okun aiye" ni kiko, șe pe oluwarẹ jẹ ẹniti ko tẹle Igbagbọ t'Ọlọrun Mẹtalọkan: eyi ko ri bẹ rara. CARDINAL NEWMAN ni orukọ ẹniti o ro orin na, nigbati o bọ sinu isin Aguda (*Roman Catholicism*) lo șe orin na; bẹni awọn Aguda ko șai gba Isin Ọlọrun Mẹtalọkan gbọ.

3. Oyenẹyẹ fo 're nipa ti ẹnikeji ti o ni oluwarẹ jẹ ẹniti ko gba Isin Igbagbọ Mẹtalọkan gbọ, to si kọ orin yi "Ngo sunmọ Ọ Ọlọrun": Miss SARAH ADAMS ni orukọ Iya abi ọlọla na njẹ, ko si gba Isin Mẹtalọkan gbọ.

ED.—EKO AKETE.

---

MR. E. ADE. OGUNMOKUN,
*GENERAL TAILOR.*
47, Princes Street, Recently Established.
*Try me and see.*

## "WOSIKA."

*Lati ọwọ Ẹni-Ọwọ I. O. Oyekunle.*

*Si Editor* "Eko Akete,"

Mo tọrọ gafara lati gba mi ni aye diẹ ninu iwe irohin rẹ lati sọrọ nipa Irohin kan ti o tẹ mi lọwọ lati ilu kekere yi ti a npe ni Ogere ni Ijẹbu Rẹmọ awọn agbalagba lo npa lowe pe "Bi ọmọde ko ba mọ'tan a gbọ atọba" to to o, mo bẹru agba. Gẹgẹ bi a ti gbọ itan ilu yi lẹnu awọn agba, a gbọ wipe lati Ipilẹṣẹ wa, o jẹ ewọ fun wọn lati ma ṣe Egungun. Awọn oriṣa pataki ti wọn nbọ ni ilu na ni (1) Onipakala (Agbeni ma dẹyin) (2) Oro (3) Agẹmọ (4) Ọbalifọn. Awọn oriṣa mẹrin wọn yi ni wọn nbọ lọdọdun. A gbọ wipe lakoko laịlai nigbati aiye ṣi wa ninu okunkun, ti ko si imọlẹ ọrọ Ọlọrun, enia ni wọn fi nbọ Onipakala, awọn ọpọlọpọ enia ti o ba si ṣe aṣemaṣe, Oro a si mu wọn jẹ, ṣugbọn nigbati imọlẹ ọrọ Ọlọrun ti tan kakiri agbaiye, ti o si de ilu yi lati ọwọ awọn Ijọ C.M.S. ati ti Ijọba Igẹsi si ti sofin ati ma fi enia rubọ ni iru iwa buburu yi ti wọlẹ gbarigbari Ki Ọlọrun maṣai sun Ẹmi Ijọba Igẹsi ati ti awọn C.M.S. siwaju fun wa. Lati nkan bi ọdun 1893, ti ọrọ Ọlọrun ti de ilu na, ati agbegbe rẹ lati ri awọn ọpọlọpọ abọriṣa ti nwọn ti di Onigbagbọ ṣugbọn bi awọn baba wa ti npa a lowe pe "Ki iburuburu ko ma ku ẹnikan mọ ni" awọn ko gbọ sisun ko gbọ sise ninu awọn abọriṣa yoku ko fi isin ibọriṣa yi silẹ, Ṣugbọn awọn bi Owolaja (Aṣiwaju) ati Ṣobọwale (Losi of Ogere) ati awọn ọpọlọpọ ti aye ko si fun wa lati darukọ duro ṣinṣin ninu Ipe wọn bi Onigbagbọ. Ọpọlọpọ inunibini ni awọn wọnyi ri, ṣugbọn sibẹ sibẹ wọn ko bọju wẹhin.

Ni akoko wọn yi ọdun oro jẹ ọdun ti gbogbo abọriṣa ma nawo, ti awọn agbẹ ʔosi bọ lati oko, ẹnikẹni ki isi lọ si ibikibi, wọn a ma jẹ wọn a si mi mu, Gbogbo awọn obinrin ni nwọn nsemọ sile [illegible]ori "Obinrin ko jẹ f'oju kan oro, ki oro ma gbe" bi ogun enia a ha gaga mọ inu iyara kekere kan, nigbati o ba si di ọjọ kẹta wọn a si ṣi wọn silẹ, ṣugbọn ni iwọn ọdun diẹ sẹhin, ko sa si ohun ti o wa ti ko lopin, a gbọ wipe Ijọba fi opin si pe ẹnikẹni ko tun gbọdọ ṣe oro mọ ni ilu na, bi wọn ba fẹ bọ oro wọn, wọn le bọ loru lati iwọn agogo mẹsan di agogo mẹrin arọ ki wọn si kogba sile. O jẹ ohun ti o dun mọ awọn Onigbagbọ lọpọlọpọ lati ri wipe Ijọba fi oke le wipe a ko gbọdọ tun ṣe oro mọ ninu eyiti awọn obinrin yio ma se mọ'le lọsan gangan.

[*Koi ti pari.*]

---

## Open Letters.

TO CELEBRITIES, NOTORITIES, ETC., IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

No. 26.

To

HIS EXCELLENCY

SIR FREDERICK GUGGISBERG, K.C.M.G.

*Governor and Commander-in-Chief of the Gold Coast Colony.*

c/o The Editor *West Africa*,

Temple Bar House, 28 Fleet St.,

London E.C. 4.

YOUR EXCELLENCY,

Your recent remarks in England on the occasion of a dinner given by Mr David Jones, J.P., at which you were the guest, regarding the "opinion" expressed—indictment, I call it—on the African Medical Practitioners in the public service or out of it in British West Africa, in which you were reported to have said *inter alia*,

> "the next step is the building of blocks of dormitories for our medical students, so as to avoid sending these young Africans home to England to become doctors, because I can assure you from my own experience that of 50 per cent. of these African doctors, their value is not worth the paper that their certificates or degrees are written on"

came to me like a bolt from the blue.

It is presumed that your exalted station as the King's Representative, gives you first-rate opportunity to make the pronouncement, which is regarded in many quarters as sweeping as it is ungenerous: of course, you readily admit that there are some belonging to this body who, to quote your *ipssima verba* "have been a conspicuous success" in their work for suffering humanity. Be this as it may, those to whom your words apply will undoubtedly leave no stone unturned in taking your Excellency to task by your being asked to furnish them with chapter and verse in which a statement such as this can find any justification whatever. Far be it from me to suggest that when at the height of innocent hilarity wines were flowing freely and merrily on the festive board, the ominous words escaped at an unguarded

moment: after all said and done, the sentiments to which you gave vent on African Doctors or a number of them cannot but be viewed with astonishing disgust by the *Intelligentsia* of British West Africa *racy of the soil.*

**It is hoped by the unfortunate public pronouncement, your Excellency is not widening the gulf of Negrophobism respecting which every attempt is being made daily to bridge over.**

Do I misread your Excellency's mind on the subject?

I pause for a reply.

EKO AKETE.

---

## EKO AKETE.

EKO, SATURDAY, JULY 14, 1923.

---

### AIYED'ERU GOLD GB'ODE ARA-ILU, PẸLẸPẸLẸ O, PẸLẸPẸLẸ O.

Ni akoko yi ti gbogbo enia fẹrẹ d'oku, oku alaire'tẹ, gẹgẹ bi orin Bisi, nitori owo ṣile t'o wọn ni ode nisisiyi, ni awọn kan tun dide ti nwọn tun bẹrẹ iṣẹ aiyederu lati ma fi eru ṣe iṣẹ ọṣọ-wura *(Gold trinkets)* ti nwọn npe ni iṣẹ *Gold* ti nwọn si nta lowo gerege e fun awọn enia alaimọkan, a sọ pe bi enia ba ri bi emi ni ẹgba iṣẹ eru yi ti mbẹ riri gẹgẹ bi *Gold* papa bi olawarẹ ba ṣeṣi ra a, ko ni gba to iwọn ọsẹ kan ko to di funfun o si fuyẹ ju ori afọju lọ, ni koi ti pẹ yi ni a gbọ pe Iya Afin kan ra ọkan ninu awọn iṣẹ yi, gẹrẹ bi o ti mu de'le ti o si nfi han Iyawo rẹ, (awọn ọgan diẹ ṣi nyọ pe ọwọ on tẹ ohun danindanin kan,) ṣugbọn nigbati Iyawo rẹ fi fun alagbẹdẹ wura kan pe ki o jọwọ ba on yẹwo bi *Gold* totọ ni, ko gba alagbẹdẹ yi ni iṣẹju kan nigbati o fi *Slate* ba ẹgba ti a pe ni *Gold* fun obinrin na ki o to di funfun ṣeṣe bi'oje nigbati obinrin na ri è ú yi ọwọ lo fi mo'ri t'o lọ'bosi tõ. Bi awọn enia wonyi ba le ṣe jamba bayi ni igboro ilu, melo-melo ni awọn ara oko ti awọn oniṣẹ buburu yi yio ti parọ nipa tita ohun ti ko nilari na fun wọn ni owo gereger e!!!

A fi eyi ṣe kilọ-kilọ fun awọn ara wa to ku to jẹ pe boya nwọn koiti gbọ pe awọn oniṣẹ-ina yi ti de arin wa nibi, papa wọ n obinrin ti o jẹ pe awọn ni awọn enia oni aiyederu *Gold* yi yio ma wọ tọlọ ju, pe ki nwọn kiyesara, ki nwọn ma si fi ẹ̃ ẹta, ti nwọn iba fi ma jẹun gbagi ni irufẹ ọna bayi.

Yio si jẹ ohun ti o wun ni bi awọn Ọpa Ọba ba le dabobo awọn ti awọn oni "Ba *Gold* jẹ" yi yio ma tujẹ nipa tita idarọ fun wọn ni owo ganranmayan. A si ke si awọn ara oko gbogbo ki nwọn ṣọra lọdọ awọn enia wọnyi ki nwọn ma ba ke abamọ lẹhin igbati ẹpa ko ba boro mọ; Lakotan a fẹ ki eku ile sọ fun t'oko nipa ọrọ yi, ki ẹ si jigiri lati ma gba awọn oniṣẹ abosi wọnyi l'aye.

A wi fun ẹ de'po, o ku s'ọwọ rẹ!!!

---

### MR. J. A. THOMAS.

We learn that on the 20th March last, Mr. J. A. Thomas of this place (Olin Road) a prominent youngman at Agege where he is at present doing business, was publicly installed the Olori of the Agege Christian Community, the Rev.-Superintendent D. A. Hughes, as president of the Agege Planters Union doing the presentation in the presence of Mr. J. K. Coker and others; it is further said that on one occasion, when the Resident of The Colony, Mr. Henry Carr I.S.O. visited the suburb Mr. Thomas was duly introduced to him in that capacity.

We would respectfully suggest to the local Government that this gentleman be accorded official recognition, particularly, when it will be remembered, that the appointment received the unanimous support of the Christian element, so that any questions, affecting this class of men in the place in the distant future may be expeditiously taken up, on reference to him, as in our opinion, such recognition will serve a useful purpose in the ordinary course of things, both to the governing and the governed.

## IFESI SI IWE TI LỌYA E. J. ALEX TAYLOR KỌ NIPA OHUN TI A WI LORI IDAJỌ TI A ṢE LARIN IJỌBA ATI OLUDEMI.

IV.

A YI I SI EDE YORUBA LATI INU *Nigerian Law Journal* TI OṢU APRIL, 1923.

Bi itumọ awọn orukọ wọnyi, akọwe ati iranṣẹ ti ri ninu ẹsẹ ofin 438 ti Iwe-ofin ọdaran (*Criminal Code*) ti o ṣe pe bakan na ni gbogbo enia mọ ọ, a mu eyi wa pe dida Oludemi lare kiṣe ti ọgbọn ede Ofin alaitumọ ede na daradara li o mu ki a kọ da a lẹbi eyiti Kotu kikun wa fi yeni daradara nipa bibi ẹjọ na wo.

Awọn Ọgbẹni S. Thomas & Co ti mọ tẹlẹ pe Oludemi kiṣe akọwe tabi iranṣẹ wọn ki nwọn to lọ pe e lẹjọ, eyi lo jẹki a fi ẹjọ, ti nwọn pe Oludemi yi si iṣọwọ ẹjọ ti a sọrọ lẹ lori pe "keta ati amọmọ fẹ gbẹsan lo sun wọn mu u nawo ati pe ki orukọ rẹ le bajẹ titi.

Owo ti ẹjọ yi na Oludemi to igba pọnn (£200) elo ni ẹjọ na na awọn ti o fi ẹjọ fun Mr. Taylor ṣe? ṣe awọn ti o fun Mr. Taylor ni ẹjọ ṣe si ti mura lati....................ẹjọ ilu ....................Lotọ ni nwọn ṣe eyiti nwọn ṣe na, bi o si ti ṣe pe ki a ba orukọ ati okiki ọkunrin yi jẹ li o leke okan wọn ṣa, nwọn lọ mu u gbọna odi ti o si ja mọ wọn loju, Lọya wọn si fi aibikita fi keta dide si ọran na lati ma sọ pe ẹjọ awọn jare, ti o si daju pe yio ja mọ wọn loju bi idan loju iwadi kinnikinni ti gbogbo aiye yio ba ni ṣe.

Ọgbẹni Taylor sọ pe:—

3 "Ẹniti o nṣe Iwe-irohin *Nigerian Law Journal* sọ idi rẹ ti on fi tẹ idajọ ti o ja idẹbi fun Oludemi kulẹ, ṣugbọn kili o jẹki OnIwe Irohin na ma sọrọ gbe idajọ na lẹsẹ. Ng ko fẹ sọ ohun ti mo ro pe o jẹki o ṣe bẹ."

Ẹrin pa wa pupọ si ohun ti Ọgbẹni Taylor bere yi, pe kini ṣe ti a sọrọ si ibi ẹjọ Oludemi, on na fẹrẹ le bere pe eṣe ti orun ati oṣupa fi wa l'ọrun. Ohun ti o wa bi ọrọ iranti wa lojojumọ li eyi "Niwọn igbati a wa laye, ẹ jẹki a wa bẹ," eyi to lati da Ọgbẹni Taylor lohun ohun ti o jẹ ki a lohun si ọrọ na.

Awa wa laye ki a le mu ki awọn ọbaiyejẹ le mọ pe a mbẹ laye, ati pe niwọn igbati a ba wa laye ko si ohun ti i kanwa lọwọ ko lati sọ ti inu wa si ohun yowu ti a ba mọ, enia iba buwa, nwọn iba ju wa s'ẹwọn, nwọn iba hangi (*hang*) wa, ṣugbọn ao ma sọ ti inu wa, ao si ma tẹ ẹ niwe pelu, ki ṣe pe nitoripe o tọ lasan ni, iṣẹ aigbọdọ maṣe ni. A ko mọ kini ṣe ti Ọgbẹni Taylor ko bere idi rẹ ti a fi sọrọ si ọrọ ẹjọ na, ṣugbọn ọkan da wa loju pe ibaṣepe Ọgbẹni Taylor ni yio gba ẹjọ na ro ni, ọtọ ni ọrọ ti a ba ma gbọ lẹnu rẹ kẹ.

Ọgbẹni Taylor ko fi ọjọ kan da si ọran ilu ri, niti gasikia, ojo ti o jẹ ki jẹki o fẹ da si iru ọrọ bẹ, nitorina a le ṣabuja ohun ti o jẹ ki kufẹkufẹ rẹ pọ tobẹ lori oran yi, kọ ju pe, koi mọ pe o yẹ ki on lọ fi iwe ti nwọn fi rojọ mọ Oludemi ha nipara, nitoripe ẹjọ na ti ku fin fin.

4 Ẹ tun gbọ ohun ti o wi o, "Ẹniti o nṣe Iwe Irohin ti Nigerian Law Journal ro pe ofin ti o tọka si Ipẹjọ Adohunmọ ati Iṣeṣi fini si ẹwọn ko tẹnilọrun, o ro pe bi ofin ti wa o nṣe awọn ti a ba pe l'ẹjọ ni ibi nla o nfẹ ki a ṣe atunṣe ninu awọn apa ibiti o tọkisi ninu ofin na, ati bẹ bẹ lọ." Akoko pupo ni Ọgbẹni Taylor fi ṣofo lori anpoyi lori ofin Iti arankan peni lẹjọ ati ṣiṣi enia fi si ẹwọn, o si ro pe ofin na pe (laifẹ atunṣe.) Kọ ya wa lẹnu rara, a si mọ pe ko ni ya awọn ti o mọ ọrẹ wa yi dunju pẹlu.

Bi Lọya, a mọ pe ogbogi iwe ni, ṣugbọn o dabi ẹniti ko ni agbara lati da nkan kan ṣe, awọn ti o ba si mọ ọ yio gba pe otitọ ni a sọ; o fẹrẹ dabi awọn ti a nwọ nilẹ, tabi ẹru ti a nfi kẹkẹ wọ. Laiṣe ani-ani lati igbati a ti gba Ọgbẹni Taylor si ẹgbẹ Lọya (bi iwọn ọdun mejidilogun wa) o fẹrẹ le gbagbọ pe ofin Ohun Inu enia papa (tabi ti ogun jijẹ) pe lapẹ atunṣe, nitoripe a ko ṣeṣi gbọ nijọkan kan pe o tọkasi ibikibi ti o nfẹ atunṣe, tabi ki o tilẹ damoran atunṣe ofin na, a ko mọ yala ero rẹ nipa apa ibi ofin na ti yipada tabi koi yipada lati igbati Oloye nla Birkenhead ti tun ofin na yẹwo ni wọn oṣu diẹ sẹhin. Ibaṣepe ki Ọgbẹni Taylor wa nigba atijọ boya on ni iba ṣe aṣaju ninu awọn ti nfi igbakugba ditẹ bi nwọn yio ti ṣe yọ Feargus O'Connor nilu, ẹniti o jẹ ọga tabi olori awọn ti ntun ofin ṣe nitoripe o damọran pe ki a tun nkan ṣe ninu Igbimọ nla ti ilu (*Parliament*) eyiti nwọn kọ nigbana, ṣugbọn nisisiyi nwọn gba a nwọn si fi sinu Iwe Aṣẹ Ilu. Ṣe ẹniti o mọ iwe ni Ọgbẹni Taylor, ṣugbọn ore kili yio fi iwe rẹ na ṣe fun iran tirẹ nigbati ko lo o rara? Nipa bayi a ro pe o ku diẹ ki o to fun Ọgbẹni Taylor, atajọ ti ki fi da si ọran atunṣe ibikibi ninu ofin. Isọkuso rẹ lori Ofin Iti keta peni l'ẹjọ ati Iṣini fi s'ẹwọn jẹ atunwi ohun ti awọn ẹlomiran ti da ninu ọran, kiṣe ero ti on funra rẹ.

IGBA L' OWO WÀ.

LAGOS—EKURO.

Bi awọn oyinbo ile-ọ̀wọ̀ wọnyi ti gba Ọja (*Produce*) l' ọsẹ yi ni eyi.

Ẹgbẹ Odo-Ọya (Niger Co.)
G. B. Ollivant,
Oyinbo Agbẹra (Lagos Stores
MacIver, African
Association, John Holt, Miller Bros.
Cooperative Wholesale Society Ltd.,
Jurgens Colonial Product.
£12 10 fun *ton* kan

EPO.

£24 ni ẹbọgbo awọn Ẹgbẹ oyinbo ti a daruko wọnyi gba *ton* kan.

COCOA.

£26 fun *ton* kan bakanna.

KANO—COMPETITIVE PRICES
Ground Nut—£14 10 per ton
Skins 1/9 per lb, Hides $4\frac{1}{2}$ per lb

### POSI T'O JIRE.

Ẹnikẹni le ri awọn Posi alarabara ti a ti ṣe lọsọ lati Ilu Ọba wa ra ni ile ọja Kọlade ni 40A Joseph Street, Okepopo, ati ni No. 1, Moloney Bridge St., Anikantamọ. Ọtọtọ ni iye owo wọn, lati £6. 6. titti de 25 guineas. Aṣọ oku (*Shroud*) Yọmini to funfun bi lekeleke si wa nibẹ fun tita pẹlu.

Ẹ lọ ri tabi ki ẹ kọ'we si :—

Ọgbẹni HUDSON COLE,
P.O. Box 477,
Eko.


## MR. A. KESSLER,

7, LABINJỌ LANE, WILLIAMS STREET, LAGOS.

# Pilsener Beer! Pilsener Beer!!

*One's thirst is quenched on taking a glassful*

"LION BREWERY BRAND"

**Reduced to 32/- per case.**

*A TRIAL, FRIEND.*

Ọgbẹni na ni Ọti *Beer* tò yo-lù-wá ni tita ṣile mejilelọgbọn pere ni fun Apoti kọkan. Igbadun mbẹ nibẹ ẹ jare. Ẹ rẹ̀ tọ wò.

*Telegraphic Address* :—**BANK ANTHONY**

TOKUNBO, LAGOS.

Telephone No. 1230, G.P.O. Box No. 300.

*Residence and Office 137 Tokunbo Street Lagos.*

Ọgbẹni A. BANK ANTHONY AND SONS jẹ Onişowo to nranşẹ ọja fun tita lati ilu ọba (*England*) wa. O si ma nfi ọja şọwọ sibe na pẹlu.

Diẹ ninu ọja ti o ma nra ni ilẹ yi ti o si ma nranşẹ ni wọnyi:—

Gẹdu, Rubber, Cocoa, Ekurọ, Epo. Obi, Igi Osun, Agbado. Iwo Malu, Awọ orişirişi.

Diẹ ninu awọn ọja ti o ma nranşẹ fun lati Ilu Ọba (*England*) wa fun tita ni ilu wa ni wọnyi. Aşọ orişirişi, Akara Oyinbo, Ẹran oniyọ ati ọpọlọpọ nkan miran bi iru eyi ti o ta ni ilu wa ati Posi isinku iru eyi ti awọn oşişẹ wa ko le şe ni ilẹ wa.

Wo aworan ọkan yi, wa si ri daju pe awọn oşişẹ ilẹ wa ko le şe iru re.



Irohin ko to afojuba lọ si ile rẹ ni No. 137 Tokunbọ Street wa si ri daju pe ki işe ti asọdun o ni ti talaka o si ni ti Olowo eyiti a fi igi şe tabi eyiti o je onide (Brass)

Ẹ kọwe tabi ki ẹ ja waya si i, a o si fi Posi ranşẹ si nyin nibikibi ninu *Motor Transport.*

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ.

6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9 30 a.m.
EVENING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m. | St Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. 6.30 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 4 p.m. | do. | Mr. A. Akinyemi |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 9 a.m. | St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10.30 a.m. | Ereko | Rev. D. A. Babatunmi |
| 7 p.m. | do. | Bro. S. O. Stowe |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. S. A. Pearse |
| 7 p.m. | ,, | E. E. Williams |
| 10.30 a.m. | Ọbun Eko | D. O. Mould |
| 7 p.m. | ,, | S. A. Pearse |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Bro. T. D. Shaw |
| 7 p.m. | do. | Olaboye Laleye |
| 9 a.m. | Erelu | J. H. Lawson |
| 7 p.m. | do. | Rev. I. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Bethel | E. A. Akinọla |
| 6.30 p.m. | | J. W. Bara |
| 9 a.m. | Zion | |
| 6.30 p.m. | do. | |
| 10.30 a.m. | African Methodist | Bro. L. A. Randle |
| 4.30 p.m. | | A. T. Iroko |

FIRST BAPTIST CHURCH

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | | Bro. S. M. Phillips |
| 6.30 p.m. | | Rev. J. R. Williams |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Rev. E. C. Alabi |
| 4 p.m. | | Bro. E. A. Ojo |

EBENEZER (BAPTIST)

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | |
| 6.30 p.m. | Rev. E. C. Alabi |

BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Brọ. Arinọla Ibaru |
| 7 p.m. | | Pastor. A. Adedeji Iṣọla |

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣe (Bamgboṣe Street.)

COLONIAL CHURCH (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion

6.45 p.m.—Evensong and Sermon, Rev. H. A. Lewis

SALVATION ARMY.

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

CHURCH OF GOD

10 a.m. 22 Ọdunlami Street, Breaking Bread
7.30 p.m. Campbell Street Open Air Service John P. A. Taylor, Wm. C. T. Terrel

---

MESSRS. J. R. THOMAS & SONS of Lisabi Hotel, Itori, beg to inform the public in general that they have been licensed by the Nigerian Railway to sell and serve refreshments etc. etc. to all passengers travelling on trains on up and down journey at Itori, Aro and Olokemeji Stations at very moderate prices This venture has already been opened by them to the public at the aforesaid Stations any one travelling up to Ibadan and back and needing supply of any kind of refreshment should intimate us through the Station Masters Iddo to Ibandan, and *vice versa.*

## N. V. Handlemattschappij V.H.

J. F. SICK ati AWỌN EGBẸ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l'eti *Glover Memorial Hall,* (*Customs Street,*) EKO.





Awọn Oyinbo Oniṣowo yi nranṣẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranṣẹ Mejila tabi jubẹ lọ ninu MASINI na.

---

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ Aṣoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ọgbẹni VIDAL R. COLE.

## Sorinolu's Grammar School.

*The first ever Established in Abeokuta and Ijebu-Ode since 17 years ago.)*

All Grammar School Lesson efficiently taught to Advantage and Success.

*Tuition Fess Rated by the Readers :—*

Primers I and II—3/- *per Quarter.*

Readers I to III—3/- *per Quarter.*

Readers IV and V—6/- *per Quarter.*

Classes I to III—9/- *per Qualer.*

Boarding Fee—£1 2s 6d, Monthly.

This is beside the Tuition Fee ; and includes. Lodging, Cloth-Washing, and Cooking Services

PLEASE NOTE !

Payments strictly in advance ; otherwise the Pupil shall suffer a temporary cessation from School and Boarding.

For futher particulars apply to

ARIYO ṢORINỌLU,

Iporo Ake, Abẹokuta. *Principal & Proprietor.*

---

## *The Philharmonic Band.*



Aw[illegible] oni fere yi nfun pẹtẹ, ilu nwọn si dun [illegible] oyin l' eti.

Owo ti a nfi'pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ lati lọ si ilu ki ilu.

Ẹni ba fẹ wọn, ko kọ iwe si

*THE SECRETARY.*

c/o A.afani Motors

The Marina Lagos.

## ALASE LEATHER FACTORY.
### "ILE ALAWỌ."

Awọ ẹsẹ bata (*sole-leather*) ti a ṣe daradara, ti o lẹ ti o si pupa yo, ati Awọ Hausa ni orișirișị awọ, yala ni pupa, funfun, dudu, ofẹfe, ati erișị awọ miran ni a nta ni ọpọku ọyọku.




Bi o ba fẹ wa wo Ile Awọ nla yi, ti iru rẹ ko si ni *Nigeria*, bi bẹkọ kọwe ṣọwọ pẹlu owosi :—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*. —Alawọbata, Eko.

### NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

### AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ so pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

## JACOB A. AJAYI,
*General Woollen Trader,*

has on hand Woollens in endless variety at 50, Dosunmu Street, Lagos, at

***Prices to suit everybody.***

*Call now, fortune awaits you.*

### ỌGBẸNI BEN. O. JOSEPH

Ti Ile owo G. B. Ollivant ni Ẹhin Ọgba (*Victoria Road*) fun bẹrẹ si ta ọti lorișirișị, o si fi eyi sọ fun awọn onibara rẹ lailai ati titun pe aye mbẹ fun wọn lati ma wa ba on ra ọja na lowo-lọwọ ni ẹhin Ọgba. (*Victoria Road*)

### DRESS-MAKING.

"KO-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,

119, TOKUNBO STREET, LAGOS.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,

119, TOKUNBO STREET, LAGOS.

MRS. FRANCES ADEYEMI THORPE (NEE GREEN) K'ogeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si Iṣẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ riran ni aṣa orișirișị ko ni ẹgbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ iṣẹ kọ, Ẹ lọ ri i.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.